# AFUNRUGBIN ATI IRUGBIN

## Matteu 13:1-23

## ẸKỌ 75 FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI:"Gbogbo ẹ̀ka ninu mi ti kò ba so eso, on a mu u kuro: gbogbo ẹ̀ka ti o ba si so eso, on a wẹ̀ ẹ mọ́, ki o le so eso si i" (Johanu 15:2).**

### Ọkọ̀ Oju-Omi gẹgẹ bi Aga Iwaasu

Ọpọlọpọ eniyan ni o pejọ lati gbọ iwaasu Jesu. Awọn ẹkọ ti O n kọ́ wọn yatọ si gbogbo eyi ti wọn ti gbọ́ ri; ọpọlọpọ eniyan ti n fẹ mọ ohun ti o ṣẹlẹ ni o wá, ati awọn miiran ti ọkàn wọn n poungbẹ gidigidi fun otitọ. Ọpọlọpọ ni wọn n tọ Ọ wá to bẹẹ ti ki i si aayè ninu ile fun wọn nigba miiran, ṣugbọn Jesu n fẹ ki gbogbo eniyan gbọ ọrọ ti Oun n sọ, nitori naa O lọ si eti okun O si joko ninu ọkọ lori omi nibi ti ko jinna si awọn eniyan ki gbogbo wọn ba le ri I ki wọn si gbọ ọrọ iye ti O n sọ.

Jesu a maa lọ si sinagọgu awọn Ju ni Ọjọ Isinmi lati waasu fun awọn eniyan, ṣugbọn Oun ko ṣẹṣẹ ni duro de ṣiṣe gbogbo eto ti ile isin ki Oun to le waasu. Nibikibi ti Jesu ba lọ ni Oun i maa kọ́ awọn eniyan -- lẹba oke, ni ọjà, ni eti okun. Oun a maa waasu fun agbajọ ọpọ eniyan, ọpọ ijọ eniyan ni wọn gbọ́ Iwaasu Rẹ̀ Lori Oke; Oun a si maa waasu fun ẹni kan ṣoṣo; gẹgẹ bi apẹẹrẹ, O waasu fun obinrin nì leti kanga ni Samaria. Oun ki i jẹ ki anfaani kan kọja lati sọ fun eniyan gẹgẹ bi yoo ṣe le de Ọrun.

### Gbigbe Igbesi-Ayé Onigbagbọ́ Lojoojumọ

Njẹ a maa n duro de igba ti a ba de ile isin ni Ọjọ Oluwa lati fi iwa Onigbagbọ̀ hàn bí? Njẹ awọn ọmọde ti o n ba rin lọ si ile ẹkọ ha mọ pe Onigbagbọ ni ọ nipa igbesi-ayé rẹ laaarin ọsẹ? A ni lati wà ni imurasilẹ lati sọ gbolohun ọrọ kan fun Olugbala wa, ṣugbọn "eyi ti o tilẹ sàn ju sisọrọ lọ ni lati gbé igbesi-ayé oloootọ." Ẹni ti ifẹ Ọlọrun n tàn jade ninu igbesi-ayé rẹ̀ ki yoo pé laaarin alejo ki ẹni kan to bi i leere iru ẹ̀sin ti o n ṣe. Awọn eniyan ayé a maa yara mọ ẹni ti i ṣe ọmọ Ọlọrun tootọ. Bi ẹnikẹni kò ba kiye si ẹ̀sin rẹ o ni lati jẹ pe abuku kan wà ninu ọna ti o gbà n gbé igbesi-ayé rẹ.

### Eredi Owe

Nigba ti awọn eniyan ba pesẹ lati gbọ ohun ti Jesu yoo wi, Oun a maa fi owe bá wọn sọrọ. A ti tumọ owe bayii pe, o jẹ ọrọ nipa ohun ti ayé yii lati fi oye ohun ti Ọrun yé ni. Jesu n fẹ ki gbogbo eniyan mọ ihin ti Oun mu wá, ṣugbọn O mọ̀ pe awọn miiran ninu wọn ki yoo ṣi ọkàn wọn paya si otitọ Rẹ̀; nitori eyi, O ṣe alaye fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pẹlu owe, ohun ti o fa a ti kì yoo jẹ́ gbogbo eniyan ni a o gbala.

Jesu ba awọn eniyan sọrọ nipa ohun ti o bá igbesi-ayé wọn ojoojumọ mu, awọn nnkan ti o le yé wọn. O ranti igba ti o tọka wọn si lili ti o wà ninu igbẹ. Ọkàn wọn tubọ n fa si lili ju bẹẹ lọ, bi wọn ti n fi iyanu ronu nipa awọ rẹ ti o pé, ẹwà eto didá rẹ̀ ati irisi rẹ̀ ti o wu ni, eyi ti Jesu wi pe o pọ ju gbogbo aṣọ igunwa olowo iyebiye ti Sọlomọni ọba n wọ lọ. Jesu tọka si eyi pe lili yii ki i ṣiṣẹ, bẹẹ ni wọn ki i ṣe aniyan nipa ohun ti wọn o jẹ tabi ohun ti wọn o fi bora, sibẹ wo bi Ọlọrun ti da aṣọ bo wọn daradara to! "Bi Ọlọrun ba wọ̀ koriko igbẹ́ li aṣọ bẽ … melomelo ni ki yio fi le wọ̀ nyin li aṣọ, ẹnyin oni-kekere igbagbọ," ni ẹkọ ti Olugbala kọ́ wa nipa lili.

### Gbigbin Eso

Ni akoko yii Jesu pa owe Afunrugbin ati Irugbin. Lai si aniani ọpọlọpọ ninu awọn ti o gbọ́ ọrọ Rẹ̀ ni o ti jade pẹlu apo eso ti o fi kọ́ ejika kan ti o si ti fọ́n eso ká pẹlu ọwọ keji gẹgẹ bi wọn ṣe n gbin ohun-ọgbin wọn. Bi wọn ba sun mọ ẹba oko o daju pe awọn diẹ yoo fọn ká si oju ọna tabi si aarin ẹ̀gun, gbogbo wọn si ti ri i nigba ti awọn ẹyẹ wa ṣa eyi ti wọn ri ni ilẹ jẹ. Jesu ni ẹkọ kan ti o fẹ lati fi kọ́ gbogbo awọn ti oye le ye nipa owe yii, ṣugbọn fun ọpọlọpọ laaarin wọn eyi já si itan ọkunrin kan ti o n gbin eso rẹ̀.

### Ọkàn ti a Sé Ilẹkun Rẹ̀

Lẹyin eyi, nigba ti o ku Jesu ati awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ nikan, wọn beere lọwọ Rẹ̀ idi rẹ ti O fi n ba wọn sọrọ lọna ti o jẹ pe awọn miiran ki yoo fi le ri itumọ ti ẹmi ti o wà ninu itan naa. Jesu dahun pe gbogbo wọn ni o le ye bi wọn ba n fẹ bẹẹ, ṣugbọn awọn miiran sé ilẹkun ọkàn wọn mọ́ to bẹẹ gẹẹ ti ọrọ igbala kò fi le wọle; nitori eyi ni eti wọn fi wuwo lati moye ti oju wọn si fọ́.

Oluwa ti mu ki eto igbala Rẹ̀ ki o hàn kedere to bẹẹ ti Isaiah fi sọ nipa rẹ pe, "Awọn èro ọ̀na na, bi nwọn tilẹ jẹ òpe, nwọn kì yio ṣì i" (Isaiah 35:8). Ọlọrun n fẹ ki gbogbo eniyan wá sọdọ Rẹ̀ pẹlu ironupiwada, O si ti ran Imọlẹ tootọ nì "ti ntàn mọlẹ fun olúkulùku enia ti o wá si aiye" (Johannu 1:9). Ṣugbọn Jesu ki yoo gba ọkàn ẹnikẹni là nigba ti ẹni naa ko fẹ́. Bi eniyan ba sé ọkàn rẹ̀ le si Ọlọrun Ọrọ igbala yoo jẹ́ were fun un.

**Ti a fi Hàn fun Wa**

Wo iru anfaani iyanu ti o jẹ ti wa lati igba ti Jesu ti de, lati mọ nipa ọna igbala bi a o bá yipada si I. Jesu wi fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe, "Ẹnyin li a fifun lati mọ̀ ohun ijinlẹ ijọba ọrun." Gbogbo wa ni a le jẹ́ ọmọ-ẹyin Rẹ̀ ki a si mọ ohun ijinlẹ wọnni bi a ba n fẹ lati ri igbala.

Njẹ oye ye wa, a si mọ riri eyi ni bí? Peteru sọ fun wa pe awọn wolii ti wadii, wọn si wá a jinlẹ, wọn si sọ asọtẹlẹ ti oore-ọfẹ ti n bọ̀ nigba ti Jesu ba de, awọn angẹli paapaa n fẹ lati wò o (1 Peteru 1:10-12). Ṣugbọn a kò fihàn fun wọn, ṣugbọn ohun ijinlẹ ti iwa-bi-Ọlọrun ni a ti fihàn nigba oore-ọfẹ yii – fun awa ti a ṣe tan lati fara balẹ gbọ́ Ọrọ Ọlọrun.

**Eso lati Ọrun Wá**

Jesu wa ṣe alaye owe Afunrugbin ati Irugbin. Oun tikara Rẹ̀ tabi awọn iranṣẹ Rẹ̀ ti o kun fun Ẹmi Ọlọrun ni o fọ́n irugbin Ọrun ti Ihinrere ká. Bakan naa ni irugbin naa ri – lati Ọrun ni gbogbo rẹ ti wá. Ki ni ṣe ti diẹ ninu rẹ so eso nigba ti diẹ ko so eso rara? Nitori ilẹ naa ni. Jesu ṣe alaye pe ilẹ naa jẹ apẹẹrẹ oriṣiriṣi awọn olugbọ, awọn eniyan ti wọn n gbọ́ ọrọ igbala.

Diẹ ninu awọn irugbin naa bọ́ si ẹba ọna awọn ẹyẹ si ṣa a jẹ. Ko tilẹ ni anfaani lati hù. O fi eleyi wé awọn ti wọn ka ọrọ igbala si were, ti ko si jẹ ki ọrọ naa wọ inu ọkàn wọn. Ọta ẹmi wọn mu ki wọn gbagbe ọrọ naa kiakia.

Diẹ ninu eso naa ti bọ́ sori apata. A mọ pe awọn gbòngbò eweko kékèké ko le wọ ilẹ apata. Eso yii bẹrẹ si i hù lori ilẹ diẹ ti o wà loke, ṣugbọn nigba ti gbongbo naa kan apata wọn ko ri omi fa fun ounjẹ, ohun-ọ̀gbin naa si kú. Jesu fi eyi wé awọn ti wọn gbọ ọrọ Ihinrere ti wọn si gba pe ọrọ iyanu ni. Wọn ri oju awọn Onigbagbọ tootọ ati irẹpọ ti o wa laaarin ijọ Kristi, wọn si ni ero pe awọn naa n fẹ iru ayọ̀ bẹẹ. Ṣugbọn wọn ni lati ronu ohun ti o jẹ lati wà fun Kristi. Igba yoo de ti wọn ni lati fara da inunibini nitori Ihinrere; akoko wà ti wọn gbọdọ sinmi le ileri Ọlọrun patatapa. Nigba ti iru igba yii ba de, awọn ti wọn rò pe ohun ti o rọrun ni lati gbé igbesi-ayé Onigbagbọ yoo jọ̀gọ̀ nù wọn a si pada sinu ayé.

Awọn eso diẹ wà ti wọn bọ́ si aarin ẹ̀gún. Awọn ohun-ọgbin naa hù ṣugbọn nigba ti wọn dagba ẹ̀gún fun wọn pa. Jesu ni awọn ohun-ọgbin yii dabi awọn ti o ri igbala ti wọn si sin Ọlọrun tọkan-tọkan fun igba diẹ, ṣugbọn lẹyin eyi ifẹ ohun miiran wọ inu ọkàn wọn, wọn jẹ ki Ẹmi Ọlọrun fi wọn silẹ. Wọn ti pinnu ni tootọ lati sin Ọlọrun, ṣugbọn nipa aibikita, ijafara, ati nipa pe wọn kún fun iṣẹ itọju ile wọn pupọ ju, tabi òwò wọn, wọn kò ni akoko lati sin Jesu; nitori eyi wọn pada sẹyin.

**Eso**

Ṣugbọn ilẹ rere wà. Eyi ni ilẹ ti o n fẹ eso ti o si ni ohun gbogbo ti yoo mu ki irugbin dagba. Iru wọnyii ni awọn ọkàn ti ebi n pa fun Ọrọ iye, ti o si ṣetan lati gba itanṣan oorun ati ojo, iji ati idakẹrọ́rọ́ -- ohun gbogbo ti yoo sọ wọn di Onigbagbọ tootọ. Iru awọn eniyan bẹẹ a maa so eso inu Ihinrere, awọn omiran pupọ, awọn miiran niwọn, gẹgẹ bi agbára wọn -- ṣugbọn eso ẹmi naa ni gbogbo wọn. Jesu ki yoo ba ijatilẹ pade nigba ti O ba dé ọdọ iru awọn bẹẹ lati ri eso, nitori yoo ri eso nibẹ -- iti wura, ki i ṣe ewe ti o ti di gbígbó.

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni owe jẹ?
2. Ki ni ṣe ti Jesu n fi owe bá awọn eniyan sọrọ?
3. Ki ni ṣe ti ki i ṣe gbogbo eniyan ni oye owe ti O pa yé?
4. Ki ni irugbin naa duro fun? Njẹ gbogbo irugbin ti a gbìn naa ni o dara bi?
5. Ki ni ṣe ti ki i ṣe gbogbo irugbin naa ni o dagba ti o si so eso?

Irugbin wo ni o so eso? Iru awọn eniyan wo ni a fi eyi wé?